E ma ka Irohin Imole Ni Igba Gbogbo

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofọ ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE- IMARO APA KETA
LATI OWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. II No. 53 WEDNESDAY JULY 2, — JULY 8 1958 KỌBỌ KAN (1d)

# Olola Oladapo Ademola Ko Ku

ABEOKUTA

IROHIN GBOJI KAN KAKIRI IGBORO ABẸOKUTA WIPE ALAIYELUWA, SIR LADAPỌ ADEMỌLA, ỌBA ABẸOKUTA WO AJA, KINLA! LEE WI BAA, GẸGẸBI EDE ẸGBA.

Bi ere, bi ere irohin na ngboji kan o si tilẹ milẹ kiji-kiji tobẹ ti a gbọ pe nṣe ni awọn ijimi enia bẹrẹ si rọ girigiri wa si afin lati wa woo, bio bajẹ wipe lotitọ ni ilẹ b a j ẹ. Ẹnu ya awọn ọmọba jọjọ si iru awọn alẹ o airotẹlẹ nwọnyi.

Nigbana ni nwọn wa bẹrẹsi fi imu finlẹ, tani ẹniti o tan irohin eke na kalẹ. Nibin ni ọwọ gbe tẹ ogbẹni kan ti nwọn npe ni Lawani Sunmọnu ti o ngbe adugbo Lukosi nwọn si faa le ọlọpa lọwọ.

AWỌN olopa sọ wipe ni ọjọ kan ni nwọn ri Lawani Sunmọnu wọ Afin Ọba wa ti o nkigbe wipe, ki nwọn fun on laye lati sinku Alake. Nigbati ẹnikan ko dalonun, lo ba bẹ sarin ilu, ti o si ntan irohin na kakiri pe A l a k e ti ku, ṣugbọn awọn Ologboni ko fẹ gbe oku rẹ fun on.

ADAJỌ bere lọwọ ọkunrin na pe kinni ohun ti o ri sọ si ọrọ yi ?

O dahun pe, nitotọ ni on TAN IROHIN NA KALẸ. Ohun ti jẹki o n ṣe be ni pe, on fẹ fi jẹun lọdọ Ọba ni.

NIGBANA ni Adajọ Kotu Ake Grade "A" sọ wipe, ẹṣẹ nla ni ẹṣẹ ti Lawani ṣe yi, ṣugbọn nitori ti o je alagba, ki o lọ si ẹwọn oṣu kan kabọ.

## Ijebu tun gbe owo won de

IJẸBU

Irohin ta si wa leti wipe Owo Ijebu (Counterfeit Notes) ti tun gbojikan larin ilu Eko nisisiyi ati ogidinleje rẹ ni nwọn ti na si arin ilu, eyi jẹki awọu ọlọpa fura wipe o nilati jẹ wipe ni Ijẹbu Ode ni ibujoko ibiti nwọn ti nṣe iru owo be.

Nitori idi eyi, ogunlọgọ awọn ọlọpa lo ya wọ igboro Ijebu lati ma fi i m u finlẹ ṣe iwadi apa ibiti ẹrọ owo na gbe wa.

Nisisiyi ọwọ awọn ọlọpa titẹ ọkunrin kan ti nwọn npe ni Salu Okupẹ nitoripe, awọn ọlọpa ba o w o korẹnsi ẹoni pọun kọkan igbaolemarun mọ lọwọ ti gaogbo rẹ si jẹ owo Ijẹbu.

Ọkunrin kan ti anpe ni Latifu ni ọwọ tun ba fun ẹṣẹ kanna yi, ati awọn ọkunrin meji kan ti o njẹ Ishọla ati Raimi.

Awọn ọlọpa si nwa awọn yoku bi a ba ti gbọ ọrọ na si, ẹo ma gbọ.

## IROHIN IMOLE di omo odun kan

ẸNI ọdun ba dun ba laiye, o tọ o si yẹ ko fi t - kantọkan dupẹ lọwọ Olodumare Baba.

Nitorina ẹnu awa Irohin Imọlẹ ko gba ọpẹ fun ajọyọ na,fun abo Rẹ nlala ti o ti fi ndabobo wa lati oṣu kejila titi di asiko yi.

A dupẹ gidigidi lọwọ ẹnyin okawe wa jake-jado fun adura Olodumare ki o tan Imọlẹ si okunkun olukuluku yin. Nitorina a bẹ gbogbo ẹnyin okawe wa pe ki ẹ ba wa wo iwe mimọ Ẹksodu ori kini ẹsẹ kejila "Njẹ lọ nisisiyi, emi yio si pẹlu ẹnu rẹ, emi o si kọ ọ li eyiti iwọ o wi."

Lẹhinna ki ẹ ba wa gbe orin yi.

Tan 'mọlẹ Rẹ si wa
Loni yi Oluwa:
Fi ara rẹ han wa
N'nu ọrọ mimọ rẹ
Jọ m'ọkan wa gbona,
K'a ma wo oju Rẹ,
K'awọn ọmọde le kọ
Iyanu ore Rẹ

## Edegbarun Omode Ni Yio Bere E'ko Ofe

Irohin pataki ti a ri gbọ lati ọdọ awọn alasẹ eto ẹkọ, ni wipe ẹ d ẹ gb a r u n ọmọ Ile-iwe l'Eko ni yio ni anfani lati bẹrẹ ile-iwe ẹkọ ọfẹ ninu ọdun ti o nbọ.

Irohin na fi nye wa wipe lẹhin igbati wọn ti bẹrẹ ẹkọ ọfẹ yi, ile-iwe mọkanlelogun ni nwọn ti kọ si Eko ti nwọn si ti nlo lọwọnwọn si tun nkọ awọn mẹdogun miran nisisiyi ti nwọn yio si fun lilo li aipẹ.

Ile-iwe St. Peter ti o wo pa ọmọ mẹjọ ninu osu

( Wo Oju Ewe Kẹfa )

FREEHOLD HOUSES FOR SALE
ITIRE ROAD ESTATE, SURU - LERE
NEWLY BUILT DETACHED FREEHOLD HOUSES
( THREE AND FOUR ROOMS )
Prices From £1,320
Over half this Estate has now been sold
Inspect Show House at Race Course
Reasonable Mortgage Terms arranged
FULL DETAILS FROM :
LAGOS EXECUTIVE DEVELOPMENT BOARD
( ESTATE DEPARTMENT )
Reclamation Road, Lagos Telephone 20384

Egbe Olorunsogo Trading Company oro
GBE MORRIS MINIBUS LC 9740 JADE LONI.
Eyi ni awọn ọjọ ti Motor yio ma kuro ni Eko.
MONDAY, WEDNESDAY, FRIDAY
Eyi dẹ ni ọjọ ti yio ma kuro ni Ọtun Oro
TUESDAY, THURSDAY, & SATURDAY
Tẹ ba fẹ wọ Motor yi ni Eko, ẹo lọ si:-
28 Idunmagbo Avenue c/o Mr- Michael O. Awoyale
Motor yi ko gba ju enia mẹtala lọ.
Agogo mẹsan owurọ ni Motor yi yio ma kuro ni Eko ati ni Ọtun Oro pẹlu.
Manager: M. O. AWOYALE

# IMOLE

ẸSIN ỌRỌ WA:-
IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA

*Editorial Works & Office*
**16, Bamgbose Street Lagos**
**Telephone:- 21985**

United Kingdom Representative
Publishing Distributing Co. Ltd. Mitree House 177, Regent Street, London W. 1.


## Tan Imole si Okunkun Wa

NI atetekọṣẹ Ọlọrun da Ọrun on Aiye. Aiye si wa juju, o si ṣofo okunkun si wa loju ibu: Ẹmi Ọlọrun si nrababa loju omi. Ọlọrun si wipe, ki Imọlẹ ki o wa: Imọlẹ si wa Ọlọrun si paala si agbedemeji Imọlẹ ati okunkun.
ỌLỌRUN si pe Imọlẹ ni ọsan ati okunkun ni oru. KI Oluwa maṣe wa ni ẹni okunkun. Ti alejo ba wọ ilu ti o ṣe alejo titi yio di ọmọ onile. Dajadaju a ti kuro ni ajoji a ti di Igi Araba, a ti wa fun gbogbo ẹnyin ọkawe jakejado, Oluwa ko ni jẹki ajọṣe wa bajẹ.

IDUPẸ

Ẹniti a ṣe Lore ti ko dupẹ o dabi ẹniti ọlọṣa ko lẹru lọ, toto oṣe bi owe NITORINA awa oniwe Irohin Imọlẹ dupẹ pupọ lọwọ wọn aṣaju wa awọn ẹni bi Ọgbẹni S. M. Ademuyiwa, Olotu, Irohin Yoruba. Ọgbẹni Tajudeen Thompson Olotu Irohin Eleti-Ọfe pe nwọn ṣe wọn ku suru igbagbogbo Oluwa ko ni gba yin lọwọ wa Iwaju, iwaju ni Ọpa ẹbiti nre e si Iwaju ni ao ma ba yin. (Aṣẹ)
BAKANNA ni a si dupẹ lọwọ gbogbo ẹnyin ọkawe kakiri gbogbo agbaiye pẹ ẹku lakaye ẹ si tun ṣe ti ẹ jẹ ki Iwe Imọlẹ na ma tan kakiri, ki Oluwa tan Imọlẹ rere si ile ati ọna olukulu n wa.

Lakotan a dupẹ lọwọ Ọgbẹni J. O. Shoyinka Onitan Ayunọrunbọ ati Igbo Ọrọ Abidodo Meje ati Ọgbẹni Afọlabi Ọlabimtan awọn wọnyi pataki tu bọ mu ki orukọ na tu-bọ ma mọlẹ siwaju si Ki Oluwa tan Imọlẹ si ọna wọn.

# Iwe Si Olotu

## Afara Ajassepo si ona Oro nfe Atunse

INU mi yio dun bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi laye lati bẹ ijọba ariwa ( Nothern Region ) lati ba wa mojuto afara (Bridge) Ajassepo ti o wa lọna Oro.

On paṭaki ti o mu wa kọ iwe yi ni wipe ninu ọmọ karọ ojire ninu ọmọ ile Igbomina ti o jẹ wipe bi a ba ti kuro ni ilu Offa tan wipe koma ori gba afara na, kosi si ẹniti ki gba ori afara na lọ si ilu rẹ. Ki ẹ si wo gbogbo orukọ ilu ti a wi wọnyi, kosi si ninu ile Igbomina ti o ni owo ori rẹ jafara, nitoripe ori afara ti a nwo yi, mọto ko le rin ni ori rẹ rara.

Lẹhin eyi, a si tun bẹ Ijọba Ilorin ki wọn jọwọ ki wọn ba wa ṣe ile Iwosan si ilu Ajassepo ti awọn abiyamọ yio ma bi ọmọ si tabi ẹniti ara rẹ ko ba da nitoripe ọpọlọpọ aisan ni o pọ ni ori ilẹ nisisiyi, ọpọlọpọ enia si o nku si aisan na nitoripe wọn ko ri onitọju, ọpọlọpọ si ni awọn ti ki gbadun bẹ ti wọn ngbe wa si Eko lati wa tọju, omiran, wọn a gbe lọ si Oshogbo lọ tọju nitorina, a bẹ yin gidigidi ki ẹ tete ba wa ṣe nkan wọnyi nitoripe ẹlomiran a wa ninu aisan ti a wi yi ti ko si ni jẹ gbe lọ si ilu miran, orisirisi awọn enia si ni wọn pọ ni ilu yi, ṣugbọn ile iwosan ti ko si ni ilu yi fi abuku kan pupọju.

Mo dupẹ aye ti ẹ gbami Olotu, Oluwa yio tun tiyin ṣe o. Amin.

Emi ni
Salami Arowoṣafẹ
Ajassepo

## E ba wa tun ona Igbele si Atan se

Inu mi yio dun bi Olotu bale gba mi laye lati bẹ awọn ijọba Iwọ-Orun wipe ki wọn ba wa tun ọna Atan si Igbalẹ ṣe, nitoripe o ti bajẹ pupọju ninu ojo yi, a ki ribi rin si nibẹ gbogbo rẹ lo kun fun ẹrọ, a ko ri aye gun kẹkẹ ologere, papa ibi afara odo Igbale ti awọn Ijọba ti nba wa ṣe ri, a ko ri wọn ki wọn ba wa ṣe mọ, a ki fi owo ori ṣafira ni sisan o, a bẹ nyin lọpọlọpọ o.
Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi o. Ọkọ ọba ko ni sayin lẹsẹ o. Olodunmare a jẹki ẹ ma ri ṣe o.

Emi ni
Ọmọ Igbele Ajana Village
Attan, Via Ọtta

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye lati bẹ awọn Ijọba ibilẹ ọna Mushin pe ki wọn ba wa tun oju ọna Mushin ṣe, ati pe ki wọn ba wa tun ina (Electric) ṣe, apakan ninu awọn ina wọnyi nibi adugbo onifade ati Martin St. wọn ki nmọlẹ dada gẹgẹbi ti titi Alakija, Ladipọ ati bẹ ni awọn oju ọna gbogbo ti o wa ni Mushin, diẹ ninu awọn adugbo na niwọnyi, Akintan St., Labinjọ, Martin, Ogungbayi ati Onifade, ko tilẹ si adugbo to dara ninu gbogbo wọn.

Ẹjọwọ ẹ ba wa bẹ awọn Ijọba Ibilẹ Mushin ati pe mo si ro wipe ẹ o fi eyi si ero.

Mo dupẹ lọwọ Olotu Irohin Imọlẹ fun eyiti wọn fi gba mi lati sọrọ sinu iwe yi.

Emi ni
Arẹmu Adewale
Mushin


***EBENEZER'S ALMANACK* 1959**

WILL BE ON SALE VERY SOON

*Printed in Two Colours and on good paper*

6d a copy, 4/- a dozen
Postage extra.

Apply to :-

Ebenezer Adedamola
16, Bamgbose Street,
LAGOS.



**E ma ka iwe Irohin Imole nigba gbogbo**


# Awon omo ile Naijiria ti o lo tetafo ere nilu Cardiff



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ ilẹ Naijiria ti o lọ ba wọn tẹtafo ere idaraya ni ilu Cardiff. Orukọ wọn niwọnyi:- Ọnagbemi, Olowu, Ọdọfin ati Violet.

# Otelemuyen Nki Nyin O

## OLOTU IMỌLẸ, Ẹ KU INAWO ỌJỌ O

ỌTẸLẸMUYẸN n k i nyin a, abimọlemo ni tẹda ẹ ko ni mọ oṣi, oṣi ko ni mọ nyin lagbara Oduduwa Aṣẹ. Ti ẹda ba nsọrọ ko maṣe gbagbe lati ma fi agbara Ọlọrun kun un.

Lọsẹ to koja, mo ti ṣe ileri pe ngo ma luwẹ nibi ikomọ ọmọ Olotu ni, ṣugbọn riro ni ti enia, ṣiṣe ni ti Odumare, ọjo to ku ọla ki ọjọ ikomọ pe ni mo ri waya pe ọfọ ṣe mi l'Abẹokuta, nko duro mu fila ti mo fi de Abẹokuta, ni igbati mo de ọhun ni mo wa ri pe oku arugbo ni, mo jo apọnran titi ẹhin nro mi, nigbati ogogoro bọ sara tan, mo gba first class ninu kete jijo, nṣe ni ariwo nta gee, ti awọn ara ilu nya muu lati wa wo mi, nitoripe Coat ati Tie ni mo fi njo, nko ba wọn ṣaisun tan ti mo fi bẹ sinu Ajampako, oru ọjọ na gan ni mo kan ọrẹ mi ti mo ni 'o lọ dele de mi nibi ikomọ Olotu lara, nigbati o bẹrẹsi tu pẹrẹpẹrẹ bi Olotu ti ṣe ṣe inawo, o ya mi lẹnu, ko si tun ya mi lẹnu pupọ nitoripe MEGIDA KUDU ni iṣe.

O bẹrẹ lati ori irẹsi jọlọfu, o ni ki on to wọle ni o ti nta sansan, o rohin bi ẹran ori rẹ ti nṣe ṣin in si on lẹnu, nigbati o ba ọrọ de ibiti ẹran ti n ṣ e ṣinsin, poto ni mo jatọ, ni kukuru, o ni oriṣi mẹta ni wọn g b e fun on, Irẹsi, ẹyin dindin, ati akara ololoro, lehinna ni awọn wa bẹrẹsi fi ọti ge yeye.

Olotu wa ọwọn, niwoyi amodun, ibeji lanti lanti. Ọtẹlẹmuyẹn ki ẹbi Olotu, Olotu papa, ọmọ Jojolo ati iyawo Olotu pe ẹ ku inawo ọjọ o, alafia Oluwa ko ma ba nyin gbe o, Aṣẹ.

# Iya Ni Wura Baba Ni Digi

## Obẹrẹ Lati Ọsẹ To Kọja

KO si ohun meji ti o fa elevi, bikose pe ọla ti bu ifọju lu wọn de aye pe wọn ti gbagbẹ o l o r e, wọn ti gbagbe ọmu ti wọn mu ati ẹhin ti o pọn wọn, adura wọn lọsan, loru, ni wipe ki baba ba tirẹ lọ, ki iya se ikan, ki awọn pa ilẹ mọ. Owo awọn elere ko han wọn, iganmu tutu nbẹ ninu firiji, ọti gidi nbẹ ninu sago owo malu nbẹ labẹ irọri

Ṣugbọn iranlọwọ ogọfa ni nwọn ko le ṣe fun obi to bi wọn, ti ogbo ti de mọlẹ, ti o nreti ipe Ọlọrun awọn obi wọn si le jẹ akasu ṣkọ meji nwọn le mu alapa, wọn si le pọnwọ la. O ti o ira, osi on are, ni awọn ọmọ nba kiri, ti nwọn nse fẹlẹlẹ kiri.

A! ẹnyin olukawe mi, "Mariwo ta nfi igbago sọlẹya, on papa nbọ wa di agbelẹ he", ogunlọgọ enia ni lo ti gun igi kọja ewe, ti nwọn ti gbe sara kọja Mọsalasi. Ki iṣe wipe a ko bi wọn re rara o, ṣugbọn, akẹju ti ba ọmọ olowo wọn jẹ, kaka ki wọn tun ara wọn bi, nwọn ti ta golu fi ra baba, wọn ti ta fadaka fi ra o je, ẹmu ki imu irin ti lagbẹdẹ ni wọn nba kiri Awọn nwọyi ti di Atitẹhi, ayọ ni pa enia, nwọn ti di ọmọ adanu nwọn abu Baba bi ẹni la oyin, wọn a wẹ iya wọn bi ẹni fi epin oyinbo fọ igba.

A! ẹnyin ọmọ enia, Iya ni wura' Baba ni digi

# Ijo Enia Dudu Ni Ilaro Egbado Se Bebe

ILU Ilaro undun yungba fun ayọ sisi ile Ọlọrun atunko oni Tawa meji ati fifi Eni Ọwọ J. ỌLA ṢOYẸLE si ori Ijọ na.

Lati ọjọ ẹti ti ise ọjọ kẹrin Ọdun yi ni awọn alejo lati orisirisi Ilu ti nrọ wa si ilu Ilaro fun ẹyẹ ti isin iṣile ati ifi Alufa sori Ijọ, Jehovah Jireh African Church ni ilu Ilaro.

Ni owurọ ọjo abamẹta ti ise ọjọ karun osu kẹrin ni agogo mẹwa, lẹhin ti Ẹni ọwọ Bishop A. Aboyẹde Cole ati awọn Alufa abẹ rẹ ti pesẹ, Ti Olu Ilaro Ọba Adekunle Ọjọbọ pẹlu awọn oloye rẹ si ti pesẹ si ita Ile Ọlọrun t i t u n yi. Awọn ero Ijọ ko si ni onka lati gbogbo ilẹ Ẹgbado wa.

A bẹrẹ isin na pẹlu orin Mimọ (Hym 577) apa keji, a si to lọ si idi ilẹkun abawọle, Baba ẹgbẹ ijọ ẹniti ṣe alagba D. L. Olurin si bẹ Bishop lati ya ile Ọlọrun na si Mimọ. Bishop si da lohun lesẹ kanna pe on setan lati ya si Mimọ Bishop si ṣaju awọn Alufa tẹle pelu awọn ẹgbẹ akọrin npọn si ka Ps. 84 yi ile ile Ọlọrun na ka. Bishop si fi ọpa rẹ kan ilẹkun ni igba mẹta, Oba Olu Ilaro ẹniti o jẹ ọkan ninu ero Ijọ na si tẹ iṣika bọ ilẹkun na, o si si, bayi ni gbogbo awọn oloye ti a ti yan si bẹrẹsi ṣi awọn ilẹkun ti o ku pi ka. Bishop si wọle o bẹrẹ iyasi Mimọ pẹlu Ps. 122 bẹni olukuluku si mbọ si aye rẹ titi ile Ọlọrun na ko fi gba ẹsẹ mọ.

Lẹhin orin 277 pelu ọrọ iyanju diẹ lati ẹnu Bishop A bẹrẹsi pe awọn Oloye lati si awọn ferese ati awọn ohun elo Ile na. Larin eyi ni Baba Ẹgbẹ Ijọ D. L. Olurin mu alufa J. Ọla Ṣoyẹle onise ijọ yi ati awọn agbegbe rẹ wa si iwaju Bishop lati fi le ori ijọ pẹlu rẹ.

Bishop si mu ẹni ọwọ yi bura gẹgẹbi eto. A si bẹrẹ iya si Mimọ pẹlu ifi alufa sori Ijọ yi ka gbo gbo ohun elo ile Ọlọrun a fi iwe aṣẹ fun Alufa Ijọ yi, a si gbadura fun pẹlu ibukun.

Lehin ifilọ kukuru lati ọwọ Alufa Ijọ yi ni Bishop gun aga iwas u, o si yan ẹsẹ ọrọ rẹ lati inu iwe Mimọ eyi ti se i w e kini Mose - Gen. ori 22 ẹsẹ 14 ( o si pe orukọ ibẹ ni Jehovah Jireh ) gẹgẹ bi orukọ ijọ yi gan. Awọn ọrọ ti o nti ẹnu oniwasu jade dabi pe ki o ma kuro nibẹ mọ o fun gbogbo ijọ ni iṣiri pẹlu itan ti o rọ mọ ẹsẹ ọrọ yi ni iwasu ati lẹhin.

Gẹre ti iwasu kọja ni awọn Alufa lati Ijọ wa ni ilẹ Ijẹbu ya wọle, larin iwọnyi oni duru wa Ọgbẹni I. A. Egbeolu nfi ika ọwọ rẹ dabira lori duru ile na, ohun orin Ẹgbẹ akọrin dabi ohun orin awọn Angẹli.

Bayi ni a pari isin na ti a si bẹ si ita ti ijo, jijẹ ati mimu sọlẹ, ti ile ndun papa agbegbe ile Ọlọrun ti ni Modeolu nipataki.

Wo Oju Ewe Karun


# EMPIRE *Aristocrat*

The Stationery Stores hereby announce that they have been appointed the Sole Agents of The "EMPIRE ARISTOCRAT" Portable TYPEWRITERS



The "EMPIRE ARISTOCRAT" Portable Typewriters manufactured by the British Typewriters Ltd. of Bromwich, LONDON.

A REALLY MODERN PORTABLE TYPEWRITER FOR EVERYONE WITH WRITING TO DO...

GUARANTEED FOR ONE YEAR — WEIGHS ONLY 9. LBS. PRICE £21

Leaflets, Sales and Service :-

**The Nigerian Office Stationery Supply Stores**

196, Broad Street, P. O. Box 148, Phone 22530 & 20973, LAGOS
57, Onireke Street, Phone 480, IBADAN.

# ẸTE NIGBEHIN ALAṢEJU

OLOTU jọwọ gba mi lati le fi Itan mi da awọn ọkawe Irohin Imọlẹ lara ya, Itan mi na lọ bayi.

NIGBATI Baba Ọkunrin kan ku o fi Ọgọrun pọun (£100) silẹ fun un. ọkunrin yi fi gbogbo owo na ra nkan ẹlẹgẹ gbogbo ti wọn le fọ—awọn bi Ṣago, Ife, mimu nkan orişirişi igo orişirişi digi, oniruru awo jẹun ati awọn nkan bẹbẹ lo ṣa. o fẹ lati fi wọn ṣe oowo. Ni owurọ ọjọ kan o to gbogbo elo wọnyi le ori ara wọn, nigbati o si wo titi inu rẹ dun o si bẹrẹ ọrọ isọ wipe. Ọgọrun pọun ti mo ni yi owo kekere kọ, ṣe on na ni mo fi ra awọn nkan wọnyi! Dajudaju bi mo ba ta wọn ngo jere ọgọrun pọun miran si i owo yio si di igba pọun (£200) O dani loju pe igba pọun kiṣe ọmọde owo nigbati moba si mu eyi ti mo tun fi ra ọja nje ko ni di irinwo pọun bẹ? Bi mo ba ti ni irinwo pọun owo de. Enia ko ma npẹ di olowo! Bẹni bi mo ba fi eyi ṣe oowo nko ni ṣai jere irinwo miran, bẹbẹ owo mi ndi ẹgbẹrin pọun £800. Sugbọn bi mo ba lọ ni ẹgbẹrin pọnun mo bọ si aiye, ki gbogbo enia ma kokiki mi ni. Sibẹsibẹ na ẹgbẹrin pọnun ko ni iduro bẹ, bi mo ba si tun fi on sowo nkọ, ṣe yio mu eere nla yio ti ibẹ jade nitori owo miran le ti ipa bẹ di ẹgba £2,000

Lakoko ti mo ba ni ẹgba gbogbo ilu yi ni yio mọ mi, ọrọkọrọ ti mo ba sọ ni ilu ni yio gee; Sugbọn bi mo tilẹ ni eyi lọwọ ngo ma ṣowo titi ẹegba yio fi di ẹgbaji £4,000 ti ẹgbaji yio fi di ẹgbarin £8,000 bẹbẹ ti ngo fi di ẹniti nni ẹgbẹrun pọnun £10,000 lọna ẹgbẹrun ti mo ba ti ni ẹgbẹrun pọnun lọna ẹgbẹrun ohun to ku fun mi nipe

## LATI ỌWỌ

Joseph Ade. Ayanbọla

ki nma jẹun ki nma lo aṣọ ki nma ṣe faari, ki gbogbo enia si ma kan sara si mi, ṣugbọn sibẹsibẹ ṣe owo ni enia fi nwa owo ri, ko tọ ki njoko bẹ. o yẹ ki nṣe owo diẹ si, bi mo ba fi eyini ra ọja ti mo tun ta a, owo mi yio ma sunmọ ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun 1,000,000,000,000. Akoko na ni ngo wa simi, ngo ṣẹṣẹ wa fẹ iyawo kan, ṣugbọn ọmọ tani mba fẹ ni ilu yi o? A fi ọmọ Ọba nigbati mo ba si gbe ni ni iyawo ti o ba de ile mi ngo ma gberaga sii, ṣe iyawo mi ni iṣe, owo mi n mo fi fẹ ẹ, bo tilẹ jẹ wipe ọmọ ọba, sibẹ nko de ile baba rẹ tọrọ onjẹ jẹ, igbamiran bi o ba wa onjẹ fun mi nko ni jẹ, o si dami loju pe inu rẹ ko ni dun yio ranṣẹ si iya rẹ, nwọn yio wa lati bẹ mi, nigbati nwọn ba si kunlẹ niwaju mi, yio si di mi lẹsẹ mu yio wipe jọwọ wo mi loju ọkọ mi, ṣe enyin na mọpe mo fẹran yin, nko jẹ dele fi ebi pa yin bẹ, ojo to rọ lana ni ko jẹki igi jona dada, on ni o si jẹki onjẹ pẹ bẹ loni.

Mo si bẹ yin pupọ ki ẹ wo ti iya mi ti o wa lori ikunlẹ yi, emi na ko tun ni jẹ ṣe bẹ mo, bio di kanran ki ebi pa yin, ngo lọ tikara mi wa igi nibikibi ti mo le ri.

Wo Oju Ewe Karun


# BI O BA FI KEROSINI SHELL TA'NA




ORU YIO DABI OSAN

## Ijo Enia Dudu Ni Ilaro Egbado Se Bebe

(O bere lati oju Ewe keta)

Baba egbe ijọ sọ fun wa ninu itan pe 1940 ni a ti beresi ile Ọlọrun yi, ati pe igba meta ni ijọ yi ya ti ọpọlọpọ fi ehin sile. Ṣugbọn nipa ore-ọfẹ Ọlọrun Ijọ yi mu ilaja "Wọn se ko bajẹ k'awọn ba yọ, ko le ba jẹ o 2ce Iṣẹ Ọlọrun ko le ba jẹ o.

Awọn onisẹ isin ọjọ na ni Eni ọwọ Bishop A. Aboyade Cole Archdeacons E. O. Peter, E. Ade Koku, Alufa E. F. Kuponiyi, F. O. Ọderinde, I. S. M. Williams, D. O Akinbọade, S. O. Akinde ati J. Ọla Soyẹle ẹniti ṣe Alufa Ijọ na. Adura wa fun ijọ ni pe ki Ọlọrun alabo ati olupese ki o ma pẹlu ijọ yi ni gba gbogba amin.

A si tun ki Alagba D. L. Olurin Baba ijọ, Alufa Ijọ J. Ọla Ṣoyẹle ati ero ijo yi nwọn ku ori rere ti gbogbo ohun ribiribi yi sẹlọ ni akoko wọn. Ọrọ iyin si ni "Titi de ihin ni Oluwa ran wa lọwọ de" Ẹ ku a ja ye o.

## ETE NIGBEHIN ALASEJU

(O bẹrẹ Lati Oju Ewe Kẹta)

Dajudaju anu rẹ yio se mi sugbọn sibẹ ngo fẹ fẹ lati fi ọla mi han ngo si taa ni ipa bayi.

"Ọkunrin yi ti gbagbe ararẹ nibiti o ti nsọrọ wọnyi, o ta ipa siwaju bi o ti pe ọrọ ikẹhin 'Bayi' gbogbo nkan ti o fi ọgọrun pọun £100 ra si lọ nwọn run womuwomu, Ọkẹrẹ gun ori iroko oju ọdẹ da, se ni oju ọkunrin na mọ foo.

Alaseju ko iti ini owo onla ọmọ Oba ni ipa, bi o ba ni owo tan ise ni yio ma gun Ọba ilu ni ẹsin.

Modupẹ aye ti ẹ gbami Olotu iwaju ni ọwọ yin yio ma lọ ẹ ko ni lọ ẹhin ọkọ Ọba kọni sayin lẹsẹ.

## OWE ILE YORUBA

1. Aṣẹwo ti o ngmu bia (beer) agbo ti ọmọ rẹ iba mu]ni o ngmu yẹn.

2. Ẹru ku Iyako gbọ, Ọmọ ku ariwo ta sode.

3. Ẹniti a gbe gun Ẹlẹdẹ iwọnba ni ko yọ mọ, ẹni t'agbe gun ori ẹsin ilẹ lo mbọ.

4. Kini anfani Orogbo, a pa ko lawẹ, a jẹ o koro, a tun ni ama fi igi rẹ dana sango ni ọmọ iya on ni.

5. Lagbaja ọmọ rẹ gọ, o ni ko ṣa ma ku, kini yio pa lẹhi agọ.

6. Atiro ni ti on ba ti ẹsẹ bọ abata, ko si ẹniti o le fa yọ.

7. Ti oko sisun Ọpọlọ ko le tọ si ni lara.

8. Ile njo, Asiwere nlana agbara, o ni bi ko babẹ wa kole babẹ lọ.

9. Egungun sọnu, a ni k'obinrin ma gbọ, nigbati iya ko bari ọmọ rẹ njẹ obinrin ko ni mọ bi?

10. Ṣikaṣika gbagbe alajọbi, adaniloro gbagbe ọla.

11. Arun ti nse ogoji ni nse ọdunrun, ohun ti o nse olorisa de, gbogbo olorisa lo nse.

12. Agba ko ni owo, a ni ko gbọn, olowo nse bi Ọba loko.

13. Ọbọ nlagun irun ara rẹ niko jẹ kamọ.

14. Okete fẹgun iyan, ile rẹ ko gbodo.

15. Ayan fẹ jo, adiẹ ni ko jẹ

16. Ewurẹ ti o jẹ owo paper pọun kan (£1) ojẹ onjẹ rẹ ọdun kan.

17. Ẹniti ase lore ti ko dupẹ, bi ẹniti ọlọsa ko lẹru lọ ni.

## ITUMO ALA

### AWỌN ONIBERE

1 JULIUS ỌLAYIMIKA ARARỌMI AGỌ OWU IBADAN Sọra mase lọwọ ninu biribiri ni asiko yi ki o ma ba lu ofin Ijọba.

2. TAYIBATU AROMIRẸ ILE-IFẸ Ọna owo ko ni pẹ se mọ ọ. mase sara ni igbakugba.

3. KARIMU ATOYEBI IBADAN. Nkan rere ko ni pẹ to ọ lọwọ, ṣugbọn sọra gidigidi, maṣe fi inu han ọrẹrẹ.

4. ṢOFỌLAHAN ABẸOKUTA Ire owo, ire ọmọ ko ni pẹ ya lu ọ, ṣugbọn adura lẹbọ.

5. ASAKẸ ABẸBI LAGOS Okunrin ti o nfẹ nisisiyi, ko ni fẹ ọ o ntan ọ jẹ ni.

6. KOFOWORỌLA IDỌGỌ Sọra nipa jamba moto

7. ADETUNDUN IKIRE ipalara ati iku ojiji ni itumọ rẹ.

8. OKESỌLA IKIRUN Sọra masẹ lọ si irin ajo nisisiyi ki o ma ba padanu ninu ọja rẹ.

Akiyesi:—Iwọ papa le bere itumọ ala tire. Kọwe si J. O. Shoyinka, 8, Ojo Road ( Oduabọrẹ ) Mushin.


# NISISIYI --

# Owo Oko-Ofurufu !

# Fun awon ti o ba fe se faaji

# Larin Eko si Ibadan

# Je Ponun Meji

Awọn Oyinbo Ọlọkọ Ofurufu ti a npe ni ( WEST AFRICAN AIRWAYS ) le gbe enia ni owo pọọku lati Eko si Ibadan, tabi Ibadan si Eko lati lọ ṣe faaji ọjọ meje.

Fun pọnun meji ti o kere ju iye ti a ti nwọ alọ nikan ri ni ao gba fun talọ-tabọ awọn ti o ba fẹ ṣe faaji lati Ibadan si Eko tabi lati Eko si Ibadan fun ọjọ meje.

Tete lọ gba aye tirẹ silẹ ni Ọfisi W. A. A. C. eyiti o sunmọ itosi rẹ, tabi lọdọ awọn Aṣoju wọn.

YOU, TOO, CAN FLY WAAC the modern way to travel

WEST AFRICAN AIRWAYS


## Awon AKEKO ni ILE IWE giga ti Loughborough



Kara eto ọdun marun eyiti ijọba ilu oyinbo ṣe nipa titan yika ninu ẹkọ iṣẹ ọwọ, ilọsiwaju rere ni a nṣe lati kọ ile-ẹkọ titun ati lati tubọ fẹ awọn ti o wa nisisiyi. Pẹlu awọn ile-ẹkọ titun wọnyi, ilu ọba (Britain) ni ireti ati jẹki awọn akinkanju onisẹ ọwọ tubọ pọsi larin awọn ọdun diẹ si. Awọn ti o wa ninu aworan oke yi ni Ọgbẹni D. A. Amao ni apa osi ati Ọgbẹni Barkuysti Roozeboon

